ELETI ỌFẸ
A-NSO-WON KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS; 62, Kosoko Street, Lagos. P.O. Box 467
CABLES & TELEGRAMS "ETI-ỌFẸ LAGOS" Phone 23370
VOL. V  No. 368 LAGOS,  SATURDAY  MAY. 9, 1953

# Dokita Oluwole Goke Alo

Aan nla gidigidi lo seni loso yi lati gbo ti iku Ogbeni Isaac Oladapo Oluwole ti o nse omo bibi ion alufa Bishop Oluwole.

A bi ologbe, yi sile aye lodun 1892 ni Eko, o si bere eko re ninu Ilewe C.M.S. Grammar School ni Eko o si tun je okan ninu awon omo akeko ti o koko je Ilewe giga Kings College sile.

Lehin ti o ti pari eko se tan o lo si Ilu Oyinbo ni 1913 nibiti o gbe ko ise isegun lati gba omode ni Ologbe yi ti fi ara re han gegebi ena pataki ninu gbogbo ohun ti o ba nse, ko se fi owo re sehin larin egbe awon asere. Bakanna lo se gudugudu meje nipa ile Olorun a ko si le foju ro sehin nipa ilosiwaju ilu.

Ogidiolojo awon omo ilewe lo ti se iranlowo fun ni yooku, opolopo si ni awon osise aber ti o ti ba won gbe eru won. Ni asiko Ajakale Arun ni 1918 ni Eko, ise ribiribi lo se lati fi gba emi enia la.

Ologbe yi ko feran iwa kariaj tabi lati ma pariwo ni gbogbo ohun ti o ba nse ninu aiye re. Awon eniti o ti sunmo ologbe yi, lole so nipa ainiye iranlowo ti o ti se fun won. Irufe awon enia bayi sowon jojo.

Lode toni yi, pupo eniyan lo feran karimi, ira eyi ko nse iwa re rara, eyi lo jeki iku Dokita yi ka enia laro. Laisi tabitabi ninu aiegun rere ni ologbe wa mu lo aye yi, awa Eleti Ofe ni eno wipe, pupo enia awa ti o fi sile yio ko irufe iwa rere ti ologbe yi hu lai ye kio toku. Sunre Dokita Oluwole.

# AKARA TU EPO!

Iwe kifa ati keje Mose ni ede Yoruba; pelu ise agbayanu Solomoni omo Dafidi ati opolopo Asiri miran ti awon Woli lailai ti bo mole wa di ohun kika ati Anfani fun olukuluku.

Asiri oruko Oba mimo Olodumare. Asiri bi ati se le ba awon Maleka mimo soro lojukorojo tabi loju iran. Hentu (Seal) fun Iriran. Abo Asiki Itaja, Asiki Imo, Asiki Ilosiwaju mbe ninu re.

Iwe yi ni a npe ni ede Oyinbo "The 6th and 7th Books of Moses". Sile mejogun pere ni

(15/-) Fifteen Shillings. Sure ra tire ki o to tan o.

POOJAR BOOKSHOP, 29, Ramos St. Idi-Oro, Yaba Nigeria tabi OSODI COMMERCIAL SERVICE, 58, King George Avenue, Yaba Nigeria.

# Imoran Fun Eyin Abiyamo

Eyin abiyamo e wa ra "Omorela" O dara pupo fun awon omode.

A ma je ki omode ti owo ara daradara, o dara fun otutu, Iko, ati orisirisi arun miran ti o nse awon omode ja ati abiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti le egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

**Omorela Baby Mixture**

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN

wa taba:

**Commercial Medicine Stores**

QUALIFIED CHEMIST

16, Victoria Street LAGOS.

# Irohin Lati Ilu Okere

## Irohin Nipa Ejo Oke Ode

**Eko** Nigbati Onidajo tun bere si gbo ninu ejo awon ara Oke Ode. Eniti o tun wa jeri fun awon Olopa ni okunrin Derefa Mota kan ti a npe ni Lamidi Akintola ara Ibadan. O so wipe oun ni on duro Sisa Balogun ni Eko ki on to ri awon enia kan ti o so tun on pe ki on mu won nigo ni ile Oke Ode. On siko ni agogo mefa ale on si de Oke Ode ni agogo mewa ole keji.

Okunrin kan ti a npe ni Mamudu Akande so wipe ilu Eko ni on ngbe ati wipe on mo salawo Oru on pade re ni Alakoro ni Eko laipe yi, on ri opo enia ti awon nlo si Oke Ode Akande ni on ri gbogbo awon odaran nwonyi ni ari won lojo na on gbo ti Sanni Doga so fun won pe enikeni ti o ba fe ba won lo ohun ti awon yoku ba se ni on na yio se.

Lojo na lohun on ri Suberu Ajide, Busari, ati Nuru Alade lara awon enia na nitoripe on na papa mbe larin won lojo na. Bi a ba yo Daniel Adeyemi gbogbo awon odaran ti o ku je omo ilu Oke Ode.

ati Akerele fe ki awon gba ipe, ayafi bi Alafin ba kuro lori oye. Aseburu meji ko gbogbo won gba be.

## Apakan Awon Oyinbo Ko Fe Isin Sosi

**Belgrade** A gbo irohin wipe awon eya oyinbo kan ti a npe ni Yugoslavian le take wipe awon ko fe isin Sosi mo, ati wipe Pope ni ilu Rome so oro na ni aseti gbogbo bi o ti nso oro na ni nwon nja kule.

Ijoba ilu Yugoslavia ko lati gba oro ti Pope losu titoripe orwilosu ti o nse fun won ko ba won lara mu.

Nitori ide eyi, nwon se ofin wipe, kakiri ni gbogbo ilewe, iba se ilewe kekere tabi ile iwe giga, College tabi ni University, enikeni ko gbodo fi oro inu iwe Bibeli ko enikeni.

Eyi nikan ko, enikeni ninu awon alufa Sosi ko gbodo fi oro Olorun ba enikeni soro mo awon e be Akorin ko gbodo to wa inu Sosi, beni a ko gba enikan laye lati to gere lati ma korin inu kiri.

## Awon Oyomisi Gba Agbara Kuro Lowo Alafin

**Oyo** A gbo wipe awon ara Oyo taku wipe ayafi bi Alafin ba kuro lori Oye Oba fun won, lori eyi ni Oba Ife, Oba Eko, Oba Ilesha, Oba Ila, Oba Oke-Ona, awon afobaje Oyo, awon Oloye, awon igbimo ati Olola Awolowo. Gbogbo awon enia nwonyi lo joko se igbimo.

Ejo ti awon Oyo ro ni wipe, ko gbodo tun wa lati se adajo nkan kete mo, awon ko fe Aremo nilu Oyo mo, Alafin ni nilati gba imoran ti igbimo ba fe, ki o si le gbogbo awon Basio Oyo kuro ni Afin. Alafin ko gbodo da ise kan ran si enikeni ayafi lati odo igbimo, ati owo ododun ti alafin ba ngba on pelu awon ijoye ni ni lati jijo pin a i wipe Alafin ko gbodo we lawani re lasako ti o ba mbe ni arin won ko si gbodo fi agbara mu enikeni lati sin esin ti o ba fe. Awon iyawo Alafin ko gbodo da si oro ilu mo.

Lehin eyi ni Oba Ilero ati Oyinbo Ajele se onigbowo fun Alafin nipa bibe awon ijoye ati igbimo po ki awon foriji on. Lehin eyi edekoyede tun bere latin awon Ijoye Oyo lori oro yi. Olola Bode

Look out for
KROLA
the New Flavour
SOFT-DRINK

Now Available
BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just write, Call, or Phone 37
Ikorodu Trading Company
20/28, Balogun Street,
(P.O. Box 395) Lagos.
AND
New Court Road
IBADAN



## Kini Awon Okawe Wa Nro

### Otito Ni Imam Adeen So

OLOTU,

Jowo gba mi laye ati kiris oro ti Imam Adeen so nipa awon omo Jaguda atiwipe ise ti awon eniyan nse ko suwon rara. Emi papaa fi ara mo oro yi lati ba ijoba ile Yoruba wipe, esikeji ti ti owo ba tun te ninu awon omo Jaguda na nile Nigeria ki ijoba mu iru awon eniyan be lo silu Fernando Po lati le fi oju mo ise Agbe, nitori ki o ba le mo wipe o le jija ko dara.

Emi ni
J. A. Akinoye
Apesin Kanta

### Nibo Ni Ilu Alufa Ke-ebe

OLOTU

Alufa kan ti a npe ni Ke-ebe wa se wasi ni Oke Ebute-meta, ninu wasi alufa yi o so wipe baba on ni toto je enia dudu, sugbon lati ona ilu Oyinbo lo ti wa. Ati wipe ilu ti a gbe bi on na ni a npe ni Kwebek (Quebec).

Sugbon baba alufa ti a nwi yi emi mo daju dajo, omo ilu Ilorin nise, nje bi a ba tun ri eniti o mo alufa Ke-ebe yi, ko patan te fun wa.

Emi ni
Alufa Enilowo Ake
ara Ajeso Ipo

### Janet Kingston Ti Ri Oko Re

OLOTU

Mo sope o ye ki nfi to gbogbo awon enia ti o ti okowe simi lati wipe mo ti ri oko temi le.

Eniti mo gba ife fun Alagba Woli Bamigbade, okan ninu ijo ensia Olowo, eniti agbara emi mba lo.

Idi re ti mo fi gba ife fun Ogbeni A G O Asiru ni Eko ni wipe, ko ni emi ijin Olorun Sugbon o nfe fe mi nitori ile ti mo ko. Nkan logba ife fun Ogbeni O Olorunfunmi ara Ibadan, nitori o dabi ogi wipe ko nife mi, o nfe gba ere ori mi ni.

Ogbeni S.A. Kadiri ara Sapele ni mba keko gba ife fun, sugbon o dabi eni wipe gbogbo oro ti mo so ko gbagbo emi ko ni le ba ara Galatia kegbe. Enikeji ti mba gba ife fun ni Ogbeni G. Johnson ara Kumasi Onisowo sugbon ako le o si Oke-Okun.

Ki nto ri Woli Bamgbade, Gabriel Aremu ni okan mi ti gba ife fun tele, sugbon Oke Okun ti o wa lo jeki adehun na ye.

Emi ni
Janet Kingston

### Asiso Ede Ni Eyi Je

OLOTU,

Gba mi laye lati se atunse nipa ede kan ti awon Yoruba ma npe wipe e ku ise aje. Gbolohun yi dara fun eniti o nsise tabi ti o nwa ise.

Sugbon eniti a le lo iru oro bi ri eyi E ku oro aje fun ni eniti o ti gba isimi kuro lenu ise, tabi ti o ti kole tabi ti o ti ra moto, awon lo ye ki a ma ki be.

Lati ma ki eniti o wa lenu ise wipe o ku oro aje, je asiso ede, nitoripe o si mbe nibiti o gbe nwa aje kiri. Ati pe, lati ma ki eniti o ti kole kase wipe, o ku ise aje asiso ede ni eyiyi je pelu.

Emi ni
I. A. Feyemi

### Nje Ko Nse Hausa Lo Ni Ede Nwonyi

OLOTU

Gba mi laye lati se itose awon oro nwonyi nitoripe ede na jo ti awon Hausa, awon Yoruba ko si ni itumo miran fun awon ede na ti o ju ti ede Hausa lo.

1. Anfani ko nse ede Yoruba ti Hausa ni
2. Alubarika, ede Hausa ni
3. Dansiki ko nse ede Yoruba
4. Dandogo, ede Hausa ni

Kini Yoruba ti npe oro nwonyi nigbati awon Hausa koiti de.

Emi ni
S. A. Majolagbo

## Iwe Itan Momodu ati Jesu Kristi

Awon ohun ti o wa ninu iwe na niyi:-

1 Momodu". Gbogbo itan igbesi aiye re.
2 Jesu Kristi" Gbogbo itan igbesi aiye re.
3 Iwa Momodu ati ti Jesu Kristi
4 Iyato ti o wa larin Jesu ati Momodu.
5 Bi Jesu ti se ga ju gbogbo Woli ati Anobi lo.
6 Agbo (eran ileya) pipa lododun, bi ko tise wule mo.
7 Alaye nikan nipa bi Elede dara fun jije tabi ko dara.
8 Awo Imale ati ti Onigbagbo, eyiti o dara ju.
9 Jesu tabi Momodu, tani Alagbawi Eda?
10 Bi Jesu Kristi ti se je omo Olorun.
11 asiri Meka ti awon Imale nlo.
12 Asiri Momodu ati Jesu ti Alkurani so.

Ati opolopo oro miran pataki ti a ko le so tan nihin. Bi a ti ti mu oka si ori ati ese ninu Bibeli, bese a mu oka ni sura (ori ati ese) ninu Alkurani si gbogbo oro ti a so ninu Iwe na fun eri ti o doju.

2/- Eyo kan) Post Free
20/- Fun mejila)

E fi owo ranse si:-

**Evangelist Joseph Akande**
**P O Box 45 Ogbomosho Nigeria**




Ovaltine Biscuits come to you in sealed, air-tight packages—light and crunchy, fresh and appetizing as the day they were baked in the famous Ovaltine factory. You will enjoy their crisp sweetness at tea-time or whenever you need a delightful snack.

Made by the makers of "Ovaltine" the delicious food drink

**OVALTINE Biscuits**




Appetizing and nourishing

## EGBOGI PEKU-PEKU

Ti a npe ni

## RATOIDS

Ni akara tabi eran akara a ma pa awon ekuto lati irora tabi oorun buruku. Ko lewu fun ara ile ati ohun osin

Iye owo re je Akara 2/3 Eran Akara 1/3

A nta ni Sobu:

**Banks Stores**

12, Market Street, Box 75, Lagos. tabi Phone 20698 96, King George Avenue, Yaba.

## Ikede Pataki Fun Enyin Elero Ogi!!!



A fe ki gbogbo enyin onibara wa ti e ti a owo sile fun ero yin mo ... oro na ti de si ... wa nisisiyi, o si je ... o ti agbara ... maru tabi mefa.

Die pere lodo ... ki e tete wa gba ... Enyin ti e si ti mbere ero yi, ki e tete wa ... ki o to tan.

E o rira le.

Phone 20998

**A Aisa Brothers**

1, Animashaun Lane, Lagos.






# Enjoy Your Own Songs

SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERINGS OF TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS ON




B.S. 76. Apala. "Olsfa Of Ofa"/"Ladigbolu"(Alafin Of Oyo By Ajadi Ilorin.
B.S. 77. Apala. "Sadiku Balogun"/"Moses Omokaye" By Ajadi Ilorin.
B.S. 78. Apala. "Alhadji Saliu"/Saka Bietu" By Ajadi Ilorin
B.S. 79. Apala. "Bisi Bebafe"/Late Ligal (Oni Sakara) By Yisufu Kafo,
B.S. 80. Apala. "Ganiyu Ayinde"/Alhadji Soye" By Yisau Kafo,
B.S. 81. Apala. „Amuda Afolabi"/"Mudasiru" By Yisau Kafo
B.S. 82. Apala. "Oroguo Of Ila"/"Rafat Bada" By Ajadi Ilorin

OBTAINABLE FROM:

**The Association Of Nigerian Gramophone Dealers**
THROUGHOUT NIGERIA



## Penny Bus Fares For School Children

By E. B. ADESEGUN

SIR,—It is with great joy and pleasure that one of us of the proposal by Sir Kofo Abayomi Management Committee of the Lagos Town Council to provide six buses for the exclusive use of the school-children in the Lagos Municipality at the rate of one penny per child each trip.

The provision, which has been a long-felt need and which will now come into effect as from May 1 this year, will greatly reduce the tension of inconvenience and hardship long experienced by the young and helpless school-children.

The equitable allocation of the buses among a reasonable number of our well-known local bus transporters, among whom the firms of Messrs J. N. Zarpas and Co. Ltd and Ilyas Transport Service are one, is another matter that calls for the commendation of the Management Committee under reference.

All honest-hearted people eagerly await the successful operation of the other proposed machinery which will frustrate the evil intentions of such fraudulent and heartless persons as frequently impersonate the school-children.

All of us grown-ups should not consider any sacrifice too great for us to make in catering in all directions humanly possible for the comfort and welfare of the little ones who will naturally become the future fathers and mothers of our country—Nigeria.

## Lagos To Have Rediffussion Service

At a Press Conference held recently at the Public Relations Office Lagos, Messrs. E.S. [illegible] and Harris, Chairman and Director of the Rediffusion (Nigeria) Ltd, announced to the members of the Press that the Rediffusion boxes will shortly be available in Lagos and environs.

The scheme which is primarily intended for the Western Region has started some months ago at Ibadan and from all indications the people of Ibadan are responding favourably to it.

The Rediffusion will take over the Radio Services from the P&T at a monthly subscription of 6/- per box. Subscribers will be required to pay 18/- or 3 months in advance and payment will be made every month to ensure regular payments.

There will be de-luxe boxes for the higher classes at an extra payment of £3 per box. The service will begin towards the end of June 1953.

## Vital Statistics.

The following returns of births and deaths were registered during the week ended 1st May, 1953, in the township of Lagos:-

Births: 243.
Deaths: 70.






# AGBO ABOYUN

Omi titun ru, eje titun wọ́ e A gbe t'ana danu, a gbe miran de! Idera de fun awọn aboyun ati abiyamọ. M.B.T. (Magic Blood Tonic) de, kunge-kunge lọ! Oyi, Ṣijẹdosoi, Inarun, Aiṣkale, Ọwọ, ati Ẹse wuwu, Ẹrẹkẹ-gbokan-ngbokan, Airi orun sun, Aitọ dede ati orisirisi Aisan miran miran ti o nṣe aboyun lọnu kole si fun patti o ba nlo M.B.T. O si tun dara pupọ fun abiyamọ [illegible] o afun ọmọ l'ọmu. Wa [illegible]n tire ni 4/-6d, owo ọkọ 1/-6d [illegible]2/- dozen lọdọ wa,




**The Egba Trading Aradan Stores**
[illegible]4, Denton Street, and 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2, [illegible]bute Metta,. 46, Victoria Street, Lagos Phone 44153, a tun [illegible]a si New Motor Park (Ogunpa) Ibadan





## Real Opportunity For Traders

Iron-Sheets, Cement, Stockfish, All kinds of Beers, Gin, Salt 40 lbs, Large Sweet mineral Waters, Flour,100 lbs, Caustic Soda, Stout Beer.

Buy the Medicines :-
Jedijedi and Inarun Bitter Tonics, File Tablets, Cough Mixtures, Tonics, Quinine mixture, Metatone, Eye drops, Earache drops, Toothache drops, Worm Expeller.

ASTHMA CIGARETTE

This is good for asthma Brochitis, Whooping Cough & Shortness Breath etc, etc.

While assuring you of all our best attention at all times, Buy the cheapest and Best articles and Medicine from :-

**Messrs J. A. Ajao Brothers,**
10, Egerton Road, P.O. Box 1[illegible], Lagos, Nigeria.



Printed & Published by The Union Printing and Publishi[illegible]ny, 62 Kosoko Street: P O Box 407 Lagos, Phone 23370,